# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE. TẸNI GBOGBO LAWA

No 769 THURSDAY AUGUST 13 1964 (2D)


## Ẹgbẹrun Ọşişẹ Da Işẹ Silẹ

SURU-LERE:- Ni owurọ ọjọ'ru ti işe ọjọ kejila oşu yi ni a w ọ n oşişẹ ile ti ile iwosan ti ile ẹkọ giga julọ ati awọn oşişẹ ile ẹkọ ti nwọn ti nkọ ẹkọ nipa ogun Suru-lere, l'ẹba Eko da işẹ silẹ ni owurọ ọjọ na ti gbogbo awọn oşişẹ na si to lẹ şeşe kakiri ayika ile ẹkọ giga julọ to nibi ti awọn akẹkọ nipa eto ẹkọ ogun, eyiti aw ọn oşişẹ ile ẹkọ fi gbe awọn pataki kokan lọwọ ti nwọn si bẹrẹ si ni wadi yika ile işẹ ile ẹkọ giga ti awọn kẹkọ eto nipa ogun na.

Ninn ọrọ ti akọwe ẹgbẹ awọn oşişẹ na Ọgbẹni Akin Aransi fi ye awọn oniwe Irohin wa ni pe ohun to mu awọn oşişẹ ile ọkọ na ti nwọn fẹ fi da işẹ silẹ na ni pe awọn igbimọ Alakoso ile ẹ k ọ giga julọ na kunna lati mu adehun ti Oloye Festus Okotie-Eboh şep ẹlu awọn olori awọn oşişẹ pẹlu awọn Aşofin apapọIjọba ilẹ Naijiria lori eto ẹkunwoowo oşu eyiti igbimọ oluwadi Morgan şe.

Akọwe ẹgbẹ oşişẹ na sọ pe ti nwọn ko ba gba ekunwo owo-oşu na awọn ko ni şişẹ mo titi nwọn yio fi gba owo na.

## Oloye Benson Sọ Pe :

# Ẹ JẸ KI A FI ỌLA FUN AWỌN ỌBA

Alakoso eto irohin fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati igbakeji olori ẹgbẹ Alakukọ oloye T. O. S. Benson sọ ninu ọrọ rẹ lori ija ti Alakukọ ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Dẹmọ NNDP pẹlu igbakeji rẹ ati Alakoso eto Ijọba ibilẹ fun Ijọba ipinlẹ Iwọ orun Oloye Rẹmi Fani Kayọde pari fun Ọba Adesọji Aderẹmi Oni ti Ile Ifẹ ati awọn ọmọ ile igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ Ilu Ifẹ.

Ninu ọrọ oloye Benson lori ẹrọ asọrọmagbesi eyiti oloye Benson kesi Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria oloye S. L. Akintola lati da abo bo awọn Ọba ati lati fun awọn Ọba ipinlẹ na ni ipo ọla nla ti nwọn ti wa tẹlẹ, Oloye Benson tun sọ ninu ọrọ rẹ na pe on rọ gbogbo awọn Alakukọ Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati yọ ọwọ awọn



Ọba Ijẹbu Rẹmọ



Ọba ipinlẹ na kuro lori eto ọrọ oselu ati pe ki awọn ẹgbẹ oşelu ye lo awọn Ọba ipinlẹ yi gẹgẹbi ohun elo fun awọn ọmọ ẹgbẹ osetu kan.

Oloye T O S Benson sọ pe akoko ti to fun awọn enia ipinlẹ Iwọ Orun yio mọ gẹgẹbi ipo awọn Ọba ti wa bayi ati pe gẹgẹbi awọn Ọba ti wa ni igba kan gẹgẹbi baba wa o ye ki a le mọ ipo awọn Ọba yatọ si ti awọn ẹgbẹ oselu oloye Benson tun sọ pe oyẹ ki a mọ ipo awọn Ọba fun wọn ati lati le bu iyi kun awọn Ọba Ipinlẹ na.

Oloye Benson tun sọ siwaju si pe l'oju ti on o ye ka le jẹ ki awọn ọba duro gedegbe ati pe ki awọn ẹgbẹ oşelu kan y e gba awọn ọba gẹgẹbi ẹni ti ngba bọlu, Oloye Benson sọ pe ki a bu ọla fun ẹni ti oye ati pe awọn nkan to yẹ

nwọn wa gẹgẹbi alagba fun Ipinlẹ na ati pe k i a ma şe yi orukọ awọn Ọba Ipinlẹ wa mọ iyẹpẹ nipa ọrọ eto oşelu.

Oloye Benson tun sọ pe ohun to yẹ ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun mọ ni pe a ko gbọdọ lo awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun gẹgẹbi ohun iduro eto oselu tabi ki a sọ awọn Ọba na di akọwe Alakoso eto ẹgbẹ o ş e l u kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ni ipari ọrọ rẹ oloye Benson rọ gbogbo awọn ọmọ ilẹ Yoruba, ẹgbẹ ọmọ Ọlofin ẹgbẹ ọmọ Oduduwa ati Ijọba ipinlẹ Iwọ orun Naijiria lati fi ọla totọ ati


Wo Oju Ewe Kẹfa




Oloye T. O. S. Benson
Minista Alamojuto Eto Irohin Fun Apapọ Ijọba Ilẹ Naijiria ati Igbakẹta Olori Ẹgbẹ Alakukọ

## Jamba S'Ole Onile Taji

MUSHIN:- JINIJINI da bo gbogbo enia ni owurọ ọjọ Aiku tise ọjọ kọkanla osu yi nigbati awọn ọlọpa ri ọdọmọde kunrin kan ni adugbo nọmba 6, Anipele St. Mushin l'ẹba Eko ti ọkunrin na ti ku iku ina ẹlẹntiriki ni o tọwọ bọ.

Gẹgẹbi irohin lati ẹnu awọn Ọlọpa to lọ gbe oku ọdọmọkunrin na fi ye oniwe irohin wa pe ọlọşa ni ọmọkunrin na işe. Oniwe irohin wa tun fi ye wa pẹ okunrin na si wọ aşọ sara eyi to fihan bi ẹni to nşe işẹ ni ile işẹ giga kan. Oniwe irohin na tun şe alaye ninu irohin rẹ pe Ọkunrin na si mu irin kan l'ọwọ lati fi ja ferese na wọle ati pe ọkunrin na tun mu imọlẹ ina etufu lọwọ lati fi riran wọ inu yara Obinrin na lati ri aye gbe ẹrọ asọrọ magbesi kan to wa lẹba oju ferese na.

Irohin tun fi ye wa pe ọdọ mọkunrin ọlọşa n a ko si mọ pe okun ina ẹlẹntiriki wa loju ferese na nigba-

Awọn ọlọpa to lọ gbe oku ọlọsa ọdọmọkunrin fi ye oniwe irohin wa pe ero ọmọkunrin na ni lati gba oju ferese wọ inu ile obinrin na lati lọ ji ẹru to wa ninu yara na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa p. ki awọn ọlọpa to gbe oku ọkunrin na lọ si ile iwosan lakulaku ni Ikẹja pe awọn ọlọpa kesi awọn oşişẹ ile işẹ ẹlẹntiriki lati pa ina inu ile ti nkan n a ti şẹlẹ lati le gbe oku ọkunrin na. Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe awọn ọlọpa si wa lẹnu ọrọ jamba to şẹlẹ s i ọlọsa. Nigbati oniwe irohin wa t u n ş e iwadi orukọ Ọ d ọ m ọ kunrin lẹnu a w ọ n ọlọpa, oniwe irohin fi ye wa p e nwọn

# Ajọdun Ijọmu-Kajọla Boy's Club Kọyọyọ

EKO:- Irohin koto afojuba ni ti ayẹyẹ ajọdun kini ti ẹgbẹ Ijọmu Kajọla Boy's Club, ẹka ti Eko ṣe ni ọjọ kẹsan oṣu kẹjọ ọdun yi ni nọmba 37, Olumẹgbọn Street, Eko.

Nigbati ọjọ ajọdun na ti kun ọjọ mẹta ni gbogbo awọn enia jankanjankan ti ẹgbẹ na ti fi iwe pe sibi ajọdun na ranṣẹ si ti bẹrẹsi de jakejado ilẹ Naijiria ati Oke Okun bakanna ni awọn asoju ẹka ẹgbẹ na lati Odi Olowo Mushin Enugun, Kano, Aba, Ibadan Ile Ifẹ, Ijọmu Oro, Ghana ati beẹbẹ lo ti bẹrẹsi de si ilu Eko.

Ni dede agogo mọkanla abọ owurọ ọjọ aiku ti ṣe ọjọ kẹsan oṣu kẹjọ ọdun yi (ọjọ ajọdun na) ni ẹsẹ gbogbo awọn alufa lati Ijọmu Oro, Omupo, Okeya Ajassẹ Ipo, ti pe sibi ajọdun na, ẹniti o si ṣe olori awọn alufa wọnyi ni ẹniọwọ Alfa Alhaji Mukadam Lawal, nwọn si bẹrẹsi ke alukurani nwọn si kewu na gba odidi wakati kan gbako lẹhinti awọn alfa yi pari kewu na tan ni ẹniọwọ Alfa Alhaji Mukadam Lawal wa bẹrẹsi ṣe akanṣe adura fun ẹgbẹ na ti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Ijọmu Kajọla Boys ati awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na wa bẹrẹsi na wabiwọsi owo fun awọn Alfa lati fi tọrọ adura ki ilọsiwaju ati idagbasoke le wa fun ẹgbẹ na ki o ma si ṣe si ọtẹ tabi rogbodiyan larin ara wọn pa apa ki ilẹ Igbomina le gba ominira ni irọrun, ki alafia ati idẹra si le ma ba bogbo ọmọ ile Igbomina gbe ni ile ati loko.

Lẹhinti awọn Alfa pari adura wọnyi tan ni wọn wa pa ẹran agbo nla abiiwo gangan ti ẹgbẹ ti ra silẹ fun ajọdun na.

Nigbati o di irọlẹ ọjọ na ni ijo alarinrin wa sọlẹ si adugbo yi lehinti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti lọ wọ aṣọ olowo iyebiye ti wọn da fun ajọdun yi wọn bẹrẹsi jo kakiri adugbo yi bi okoto, gbogbo rẹ si dun yungba, a fi ẹniti o kẹgan ajanaku ni yio sọ pe on ri kini kan firi, bi a ba ri erin ki a sọ pe a ri erin, awọn ọmọ ẹgbẹ Ijọmu Kajọla Boy's Club na pabambari owo ni ọjọ na.

Gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ati awọn ti o wa lati ọna jinjin ni nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ lọrun ti o fi jẹ pe ko si ẹniti ko di ẹran ati adiẹ dindin lọ si ile.

Nigbati oniwe irohin wa Ajẹgboro-dagba ti o lọ sibi ajọdun na nfi ọrọ wadi ọrọ lenu akọwe Ẹgbẹ na ọgbẹni Zaid Balogun nipa ete ati eto awọn ẹgbẹ na, o sọ fun oniwe irohin wa na pe awọn da ẹka ẹgbẹ yi silẹ ni ilu Eko fun ilọsiwaju ati idagbasoke ilu Ijọmu, ati pe ki irẹpọ ati isọkan le wa larin awọn ọmọ Ijọmu ti o wa ni Eko ati agbegbe rẹ, ki nwọn si le jọ maa jẹ anfani ara wọn.

O ṣe afikun ninu ọrọ rẹ pe awọn ni ẹka ẹgbẹ yi kakiri gbogbo ilu ti ọmọ ilu Ijọmu ba wa ki nwọn le mọ ara wọn, ki nwọn si ijọ wa ni irẹpọ ati isọkan ki nwọn si jọ sowọpọ lati ma wa ilọsiwaju ilu baba wọn paapa ilẹ Igbomina ni apapọ.

O ni gbogbo ibiti awọn ni ẹka ẹgbẹ yi ni wọn ran awọn aṣoju mẹfamẹfa wa si bi ayẹyẹ ajọdun kini ti ẹka Eko, eyiti o jẹ ẹka kan pata ki ninu ẹka ẹgbẹ Ijọmu-kajọla Boys ati pe ajọdun yi ni akọkọ ti ẹgbẹ na yio kọkọ ṣe l'Eko.

Diẹ ti aye wa lati daruko ninu awọn enia jakanjakan ati awọn ẹgbẹ ti o ran aṣoju wa sibi ajọdun na ni wọnyi: Ọlọla Sheilu Alhaji Mukadam Lawal Alfa Ibrahim Oluwatoyin Ijọmu, Yusufu Alabi Alhaji Jimọh Adebayọ Lawal Abdu Adeyẹmi Ọgbẹni Sulemọna Agbabiaka ti iṣe Baba ẹgbẹ alasowopọ ti ilu Ijọmu, Ọgbẹni Buraimọh Okelẹyẹ lati Ibadan Fatayi Okelẹyẹ Iyaafin Muniratu Owokunle (iya Tajudeen) Iyafin Ramọta Aminu (Iya Mukaila) Iyaafin Rafatu Okiki ẹga, Fidi Balogun Ayisatu Shafẹ, Ajibikẹ Raji, Sifawa Tafa, eyi ni orukọ ẹgbẹ ti o wa si bi ajọdun na ẹgbẹ Akewuṣafẹ ẹgbẹ Arowoṣaiye ẹgbẹ Imọlẹ Anobi, ẹgbẹ Ajijọla Agbobi ati bẹẹ lọ.

Eyi ni oruko awọn Olori ẹgbẹ Ijọmu Kajọla Boy's Sunmọnu Akanbi (Baba isalẹ ẹgbẹ) Karimu (Olori ẹgbẹ) Zaid Balogun (Akọwe) oludari eto ẹgbẹ ọgbẹ ni Okiki Ẹga.

Emi Ajẹgborodagba ki ẹgbẹ Ijọmu Kajọla Boy's Club ni oruko Iwe Irohin Imọlẹ pe ẹgbẹ yio ma roke o. Ẹ ku inanwo o.

## Iyawo Alakoso Nilu Oyinbo



Aworan oke yi ni ti Iyaafin Faderera Akintọla ati awọn ọmọ rẹ meji nigbati Iyaafin Akintọla fi lọ fi awọn ọmọ rẹ mejeji wọ Ile-Ẹkọ giga kan ni ilu Oyinbo laipẹyi eniti o wa ni ẹhin Iyaafin Akintọla ni Aṣoju Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ilu Oyinbo Ọmọba Ade Odubanjọ.


BO BA NI

Iwe—Titẹ

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi Iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyaw

KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE

Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Dan wa wo lẹkan ṣoṣo ko si ri iyatọ

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 769. THURDSAY, AUGUST 13 1964 (2D)

## Oyisile Sọ Pe Nwọn Ko Yọ On Kuro L'ẹgbẹ Afẹnifẹre

MUSHIN;- Ni ọjọ Aiku tise ọjọ kọkanla oṣu yi ni ọgbẹni Nafiu Ademọla Oyesile fiye oniwe irohin wa ni Mushin pe iyalẹnu lo jẹ fun on nigbati on ri ka ninu iwe irohin kan ti ise iwe Irohin Imọlẹ pe nwọn ti yọ on kuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ọgbẹni Oyesile tun fi ye oniwe Irohin wa pe ninu iwe Irohin pe nwọn yọ on kuro ninu ẹgbẹ na fun iwa ti ko ba eto ofin ẹgbẹ lọ ati akitiyan on ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti o lodi sofin ẹgbẹ na Ọgbẹni Oyesile sọ pe ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ na loti ọkọ iwe lati se iwadi pe ọjọ wo ni nwọn yọ on kuro ninu ẹgbẹ na ati pe awọn si fẹ mọ otitọ ọrọ na.

Ọgbẹni Oyesile sọ pe nwọn ko fi igba kankan yọ on kuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe on ni alaga ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre Awoyọkun ni Mushin, akọwe Alakoso ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ni Ikẹja ati agbegbe rẹ ati pe on si jẹ ọkan ninu igbimọ ọmọ ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ni ipari ọrọ rẹ Ọgbẹni Oyesile sọ pe gbogbo irohin to jade ninu iwe na pe irọ patapata ni ọrọ na.

# Ọba Ọni Fi Ere Oko Silẹ Ki Ade Ma Ba Ṣi L'ori Rẹ

EKO:- NISISIYI Ọba Adesọji Aderẹmi, Ọni ti ilu Ifẹ wa ni ominira ara rẹ ati pe o tun wa bayi pẹlu ade ori ti ko le si bayi, irohin na de ọwọ wa lati ọwọ oniwe irohin pe Ọba Adesọji Aderẹmi, Ọni ti ilu-Ile Ifẹ ti gba bayi lati fi ere oko Gẹdu ti on iṣowo ti Aderawo eyiti Ọba Adeṣọji jẹ Alakoso oko na, ati pe ija lariu Igbimọ Afuniso ti Ijọba ibilẹ ilu Ifẹ ati Ọba Ọni si ti pari lẹhin ti o ti fi oko na silẹ ati ere to jẹ lori oko Gẹdu na silẹ



Ọba Adesọji Aderẹmi

Ninu irohin kan to de ọwọ wa lati ọwọ awọn ọmọ egbẹ Ọlọfin eyiti awọn Oloye ẹgbẹ na fi ọwọ si ninu awon to fi ọwọ ṣi iwe na ni Dokita Majẹkodunmi alaga ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin ati Oloye H. O. Davies ti o jẹ akọwe ni ilu Eko ni ọjọ aiku ti se ọjọ kọkanla osu yi fi ye wa pe ija na ti pari nigbati Ọba Ọni ti gba tio si tẹ ọwọ bọ adehun pe on Ọba Adesọji Aderẹmi gba lati fi ere oko Gẹdu ti onisowo Aderawo silẹ fun Ijọba ibilẹ Ilu Ifẹ.

Ninu iwe ti awọn igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ifẹ ati Ọba Adesọji Aderẹmi jijọ fi se adahun lori eto oko Gẹdu na lọ bayi.

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni awọn asaju ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin ti awọn asaju na lọ bayi, Dokita M. A. Majẹkodunmi alaga Oloye H. O. Davies akọwe Oloye M. A. Okupe Akapo Ọgbẹni M O Onayẹmi oloye Adeyẹmọ, Oloye Akinfẹnwa, ati Oloye Oyesina ba Ọba Adesọji Aderẹmi Ọni ilu Ifẹ ṣọrọ ni Ibadan pẹlu igbakeji Alakoṣo jọba ipinlẹ Iwọ Orun Oloye Rẹmi Fani Kayọde niwaju Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye S L Akintọla Alakoso eto owo ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Ọba C D Akran Ọba Alake ti ilu Abẹokuta ati Ọlọwọ ti ilu Ọwọ.

Irohin inu iwe na tun fi han pe laseko eto ọrọ na pe Ọba Ọni gba pe on yio fi oko Gẹdu ati ere ti on Ọba Ọni ti ri ninu oko na silẹ fun Ijọba ibilẹ ilu Ifẹ. Ọba Ọni si gba pe on yio tun san owo to jẹ ere oko na fun Igbimọ Afunnisọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ifẹ eyiti ọba Adesọji Aderẹmi ti fi pamọ si ile ifowopamọ si lati oṣu kẹta ọdun 1963

Lẹhin eyi ni Oloye Rẹmi Fani-Kayọde ati Dokita Omitowoju gbera lati lọ si Ile-Ifẹ lati lọ sọ fun awọn ọmọ Ile Igbimọ Afunishọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ifẹ lati le mọ bi nwọn pari ọro na si Irohin tun fi ye wa pe awọn Igbimọ Afunishọ na si gba bẹ.

Ọba Ọni si ti fi ọwọ si iwe adehun lati fi oko na silẹ ati pe Oloye Fani Kayọde ti gba iwe adehun na lati lọ ṣe ẹto lori rẹ pẹlu Ijọba Ibilẹ ilu Ile-Ifẹ.

Ni ipari gbogbo ẹrọ na awọn igbimọ ọmọ ẹgbẹ Olofin ṣi sọ ninu ọrọ wọn pe awọn ri pe gbogbo ọrọ na si ti pari bayi ati pe awon ko si tun jẹ ki ọrọ kan tun ṣẹlẹ lori ọrọ na. Awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlofin si tun sọ ninu ọrọ wọn pe awọn dupẹ lọwọ Ọba Ọni ati Oloye Remi Fani-Kayode lori isowọpọ wọnnipa gẹgẹbi ija to wa larin Ọba na ati awọn ọmọ ile igbimọ Afnnishọ ti Ijọba ibilẹ na ṣẹ tele pari bayi.



Dokita Majẹkodunmi

## Iranti Iya Wa

MAGDALENA ỌNIBIYỌ ỌLADIPỌ

Ẹniti o sun ninu Oluwa niọjọ kẹtala oṣu kẹjọ Ọdun 1963, Odi Ọdun kan loni to fi wa silẹ

Lojoji mọ ni a nṣe iranti rẹ. Sun re, Iya Olore.

Lati Ọwọ Ọmọ Rẹ
A O Ọladipọ

## E Jẹ Ki A Fi Ọla Fun Awọn Ọba

Lati Oju Ewe Kini

eyi to yẹ fun awọn Ọba ipinlẹ Iwọ Orun. Oloye Benson tun sọ pe gẹgẹbi oti da on loju pe awọn Ọba ipinlẹ na ko fi ara wọn silẹ fun awọn ẹgbẹ oselu, kankan gẹgebi asaju wọn tabi akọwe Alakoso ẹgbẹ oṣelu Oloye Benson sọ pe idaloju wa fun awọn Ọba ipinlẹ na pe ko si ohun to le si ade lori wọn ati pe ko si ohun to le gbe wọn kuro lori oye ti nwọn wa.



Ọba Ijẹbu Igbo

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 13/8/64.